“Ayé ìgbádùn ni, eyi ti o loore ju ninu ìgbádùn ayé ni obìnrin rere”

Láti ọdọ Abdullah ọmọ Amr- ki Ọlọhun yọnu si àwọn mejeeji- pe ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Ayé ìgbádùn ni, eyi ti o loore ju ninu ìgbádùn ayé ni obìnrin rere”

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pé ayé pẹ̀lú nǹkan ti n bẹ ninu ẹ jẹ nǹkan ti eeyan maa n gbádùn fun ìgbà díẹ̀, lẹ́yìn naa ni o maa kúrò, ati pe ìgbádùn rẹ ti o ni ọlá jù ni obìnrin rere, eyi ti o ṣe pe ti o ba wo o yoo dun un ninu, ti o ba pa a láṣẹ yoo tẹle e, ti ko ba si ni tòsí o maa ṣọ́ ọ ninu ẹ̀mí ara rẹ ati dúkìá rẹ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/5794